# Àìsàn Kòkòrò Kòrónà 2019 (COVID-19)
# Àwọn Ìbéèrè Tí a ń Bèrè Nígbogbo Ìgbà

A ṣàfikún ní osù Ẹrẹ́nà 6, 2020

**Lábẹ́ ìdarí Gómìnà  Larry Hogan, àwọn ìbẹ̀wẹ̀ ìpínlẹ̀ tẹ̀ṣíwájú láti ṣèdàgbàṣókè àwọn ètò ààbò ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àti ìdáhùn fún àrùn kòkòrò kòrónà 2019 (COVID-19).**

**Ẹ̀ka Ìlera Maryland (MDH) máa ṣèbániṣọ̀rọ̀ tàrà pẹ̀lú gbogbogbò, pèsè àwọn ìmúdójúwọ̀n tí àwọn ipò yí se ń dàgbà si àti ìwífún nípa bi o se le dáàbò bo ara rẹ àti ìdílé rẹ.**

**Kíni COVID-19?**
COVID-19 jẹ́ àrùn tí kòkòrò èémí  fà ti a kọ́kọ́ dámọ̀ ní Wuhan, Àgbègbè Hubei, China ní osù Ọ̀pẹ 2019. COVID-19 kòkòrò tuntun tí kò tîì fa ibà nínú ènìyàn rí tẹ́lẹ̀. Gbogbo Àgbáyé, COVID-19 ti fa ogúnlọ́gọ̀ àrùn, fa ibà àti ni àwọn kan o ti fa ikú. O ti tàn kiri àwọn orílẹ̀dè jádèjádò àgbáyé, pẹ̀lú ọ̀pọ̀ ìjábọ̀ lójojúmọ́.

**Ǹjẹ́ COVID-19 ti tàn deh U.S.?**
COVID-19 ti tàn dé orílẹ̀dè U.S o sì ti fa kí àwọn kan ní ibà, àti nínú àwọn tó le, o ti fa ikú.

Bí ó ti jẹ́ pé àwọn ti a ṣàrídájú jẹ́ àwọn ti o ti rin ìrìàjò òkèrè lọ sí àwọn orílẹ̀dè to ní COVID-19 tó pọ, a ti rí àwọn àgbègbè ti o ti tàn dé ni U.S. “Títànkálẹ̀ Àgbègbè” jẹ́ pé àwọn ènìyàn ti ni kòkòrò ní àgbègbè náà, pẹ̀lú àwọn tí ko yé bí wọ́n se ko tàbí ibi tí wọ́n ti ko.

**Kíni ewu si gbogbogbò báyìí?**
O le jẹ́ wípé nígbà kan, títàn kálẹ̀ COVID-19 máa pọ̀ gidi. Àwọn amòye ń retí pé ní àwọn osù àti ọ̀ṣẹ̀ tó ń bọ̀, a le retí láti ri ọ̀pọ̀ àtànkálẹ̀ ní U.S. àti gbogbo àgbáyé.

Títànkálẹ̀ Àgbègbè ni bi otútù àti iba se ń ràn – ó túmọ̀ sí pé àwọn ènìyàn ń ko lára ara wọn bí wọ́n se ń gbé ìgbé ayé wọn lójojúmọ́. Títànkálẹ̀ Àgbègbè COVID-19 ní àwọn apá kan U.S. fa ìbẹ̀rù nípa ìhàlẹ̀ fún àwọn àgbègbè tókàn.

**Ǹjẹ́ ẹnikẹ́ni ni Maryland ni kòkòrò tuntun yí?**
Ní 5 osù Ẹrẹ́na, 2020, wọn kéde pé Maryland ti ní ẹni mẹ́ta to ní COVID-19. Àwọn aláìsàn tó ni

kòkòrò náà nígbàti wọ́n rin ìrìnàjò lọ sí òkè òkun, wọ́n wà ní ipò tó dára a sì ṣẹ́ wọn mọ́lé wọn.

5 osù Ẹrẹ́na, Gómìnà Hogan kéde ipò pàjáwìrì láti lo gbogbo àwọn ohun èlò. Ìkéde náà fún àti darí MDH àti Ìbẹ̀wẹ̀ Àkóso Pàjáwìrì Maryland (MEMA) láti darí gbogbo àwọn ìbẹ̀wẹ̀ ìbílẹ̀ àti Ìpínlẹ̀. Ìkéde náà tún fún MDH àti MEMA lágbára láti múra sí ìdarí pẹ̀lú àwọn ẹ̀ka ìlera ìbílẹ̀ àti ìpínlẹ̀ àti àwọn ẹgbẹ́ ìṣàkóso.

Ìwífún tó-dójú-ìwọ̀n nípa ṣíṣàyẹ̀wò àti iye àwọn tó ní ní Maryland wà ni health.maryland.gov/coronavirus. A máa ń ṣàfikún ni ojojúmọ́.

**Tani ó wà ni ewu báyìí?**

Lọ́wọ́lọ́wọ́, àwọn ènìyàn tó wà ní ewu:

- Tí ó rin ìrìnàjò lọ sí àgbègbè ibi iṣẹ̀lẹ̀
- Tó súnmọ́, farakan ẹni tó ní COVID-19
- Tó ń tọ́jú àwọn ènìyàn tó ní COVID-19

**Báwo ni COVID-19 se ń tànkálẹ̀?**

COVID-19 máa ń tàn kálẹ̀ bí otútù tàbí àjàkálẹ̀ nípa:

- wíwúkọ́ àti ṣísín, tó ṣẹ̀dá àwọn omi èémí
- ìfarakan ni, bí fífọwọ́kàn tàbí bíbọwọ́
- fifọwọ́ kan ohun tàbi ara tó ní kòkòrò

**Kíni àwọn àmì COVID-19?**

- Ibà
- Ikọ́
- Èémí kúkúrú
- Fún èyí tó bá ti le, otútú àyà (àkóràn ẹ̀dọ̀)

**Kíni kí n se tí mo bá rò wípé mo ní ibà pẹ̀lú COVID-19?**

Tí o bá rin ìrìnàjò lọ si àgbègbè tó ní kòkòrò láìpẹ́ tàbí o ní ìfarakàn pẹ̀lú ẹni tó ní COVID-19, tí o sì ní ibà, ikọ́ tàbí o kò le mí dáadáa, wá ìtọ́jú ìlera lẹ́kẹ̀kẹṣẹ̀. Gbé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí:

- Pe dókítà tàbí yàrá pàjáwìrì kí o tó lọ
- Ṣọfún wọn nípa ìrìnàjò láìpẹ́ àti àwọn tí o súnmọ́ (bí àwọn tó wà nínú ilé rẹ)
- Lo ìbòjú, tí ọ̀kan bá wà

**Tí ẹnikẹni bá ní COVID-19, kíni ó máa se wọ́n?**

Ọ̀pọ̀ ló n gba ìwòsan lára àkóràn yí. Àwọn kan ma ní àmì kékeré tàbí díẹ̀. A máa gba àwọn kan níyànjú láti lọ gba ìmúláradá nílé kí wọ́n sì yàgò fún àwọn ẹlòmíràn. Kí àwọn yí pe olùsègùn wọn tàbí olùtọjú ìlera tí àmì yí bá pọ̀ si.

Àwọn àkóràn COVID-19 le yọrí si àìsàn tó le, àti pé òmíràn le já sí ikú. Tí ẹnìkan bá ní àìsàn tó le láti ara COVID-19, a le gbà wọ́n si ilé ìwòsàn. Àwọn àgbàlagbà àti àwọn tó ní àìlera tẹ́lẹ̀ ní ewu àìsàn tó le. Àpẹrẹ àwọn àìsàn ìlera náà ni: jẹjẹrẹ, ìtọ̀ súgà, àìsàn ọkàn tàbí àwọn ipò míràn tí kò le jẹ́ ki ipá ara

bá àwọn kòkòrò jà.

**Sé kí n fagilé ìrìnàjò sí òkè òkun?**
Àwọn Ibi fún Ìdarí àti Ààbo Àìsàn (CDC) ń ṣàfikún àwọn àmọ̀ràn bi a se fẹ́. CDC ti gbàmọ̀ràn pé kí a má rin ìrìnàjò lọ sí àwọn àgbè tó ní kòkòrò. Àwọn tó ní ipò àìlera ni a fún ni àmọ̀ràn láti yàgò fún ìrìnàjò tíkò se kókó lọ si àwọn àgbègbè kan.

Ṣàbẹ̀wò si ojú wẹ́ẹ̀bù ìrìnàjò CDC láti sàyẹ̀wò àwọn ìkìlọ̀ ìrìnàjò ti o ba fẹ́ rin ìrìnàjò sí òkè òkun: https://www.cdc.gov/coronavirus/2019-ncov/travelers/index.html.

**Sé kí n wọ ìbòjú ti mo bá ń jáde?**

Rárá. À kò gba ìbòjú níyànjú fún gbogbogbò, ìbòjú le wúlò ní àwọn ibi kan – bí ilé ìwòsàn tàbí yàrá ìdúró ní ilé ìwòsàn – láti dáàbò bo ẹni tó ní àìsàn èémí láti tàn kálẹ̀ sí àwọn míràn.

CDC kò gba àwọn tí ara wọn dá níyànjú pé kan wọ ìbòjú láti dáàbò bo ara wọn lọ́wọ́ àìsàn èémí, pẹ̀lú COVID-19. O le lo ìbòjú ti amòye ìtọ́júìlera ba gbà ọ́ níyànjú. Àwọn ènìyàn tó ni COVID-19 ni ko lo ìbòjú àti àwọn tó ní àwọn àmì. Èyí ni láti dáàbò bo àwọn míràn lọ́wọ́ ewu à ti ní. Lílo ìbòjú jẹ́ kókó fún àwọn òṣìṣẹ́ ìlera àti àwọn tó ń tọ́jú àwọn tó ní COVID-19 ní àsúnmọ́ (ní ilé tàbí ní ilé ìtọ́jú ìlera).

**Kíni mo le se láti dáàbò bo ara mi àti ẹlòmíràn?**
Gbé àwọn ìgbésẹ̀ ààbò ojojúmọ́ ti a gbàníyànjú láti dín títàn kálẹ̀ àìsàn èémí bi otútù àti àjàkálẹ̀:

- Fọ ọwọ́ rẹ pẹ̀lú ọṣẹ àti omi gbígbóná díẹ̀ fún ókéré jù ìṣẹ́jú ààyá 20
- Lo aṣanwọ́ tó ni ògógóró bí ìdá ọ́gọ̀rún tí kò bá sí ọṣẹ àti omi
- Bo ikọ́ àti ìṣín rẹ pẹ̀lú tísù, apá tàbí ìgunpá
- Yàgò fún fífọwọ́ kan ojú, imú àti ẹnu rẹ
- Nù ki o sí bú aṣanwọ́ sí àwọn ohun àti àwọn ara ohun nígbàkúgbà nípa ṣísẹ ìmọ́tótó
- Yàgò fún fífarakan ẹni to ní ibà
- Tí o bá ní ibà, dúró sílé, àyàfi ti o bá ń gba ìtọ́jú ìlera

**Ǹ jẹ́ àjẹsára tàbí ògùn wà ti mo le gbà fún COVID-19?**
Kò sí báyìí, nítorí COVID-19 jẹ́ àìsàn tuntun. Ṣíbẹ̀ṣibẹ̀ àwọn amòye n ṣiṣẹ́ lórí ọ̀kan. Bí pẹ̀lú àjẹsára tuntun, a gbọ́dọ̀ danwò kó dára kí o sì jáfáfá. O le tó ọdún kan ki àjẹsára COVID-19 tó le wà.

Kò sí ògùn kan pàtó tó wà láti ṣèwòsàn COVID-19. Ṣìbẹ̀ṣíbẹ̀, àwọn tí ó bá ní COVID-19 ní láti wá ìtọ́jú ìlera láti ṣèrànwọ́ dídín líle àwọn àmì rẹ̀.

**Báwo ni mo se le gbáradì fún COVID-19?**
- Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ògùn tí a kò yàn fún ọ àti àwọn ìpèsè ìlera míràn, pẹ̀lú àwọn ògùn ara ríro, inú rírun, ikọ́ àti otútù
- Ṣàyẹ̀wò àwọn ògùn tí a yàn fún ọ pé o ni ní ọ̀pọ̀; rà si tí o bá nílò

- Ní òsùnwọ̀n ìgbóná, tísù àti aṣanwọ́ nítorí tí o bá ní ìbà tí o gbọ́dọ̀ dúró nílé láti bọ̀sípò
- Bá àwọn ẹbí rẹ àti àwọn olólùfẹ́ rẹ ṣọ̀rọ̀ nípa bi wọ́n se máa tọ́jú wọn tí wọ́n bá ní ìbà àti ohun tí ó máa nílò láti tọ́jú wọn nílé
- Ní ìpèsè omi àti oúnjẹ ọ̀ṣẹ̀-méjì ṣílẹ̀ nílé

**Ǹ jẹ́ ohun míràn wà ti mo ní láti mọ̀?**

- Má fi àbùkù kan ènìyàn ẹ̀yà tàbí eré ìje. Àwọn kòkòrò kò dojúkọ àwọn kan pàtó, ẹ̀yà tàbí eré ìje.
- Gba ìwífún kí o sì ni láti ibi ti a gbẹ́kẹ̀lé àwọn orísun ìjọba. Sá fún àwọn àròsọ, hàeṣọ àti àwọn iró tó ń kiri lórí mídíà tàbí níbò míràn. Àwọn ìwífún ìlera tí wọ́n ń pín lórí mídíà àwùjọ kò kì ń peh, àyàfi tí ó bá wá láti ìjọba, orísun ti a gbẹ́kẹ̀lé bí CDC, MDH tàbí àwọn ẹ̀ka ìlera ìbílẹ̀.

**Ǹ jẹ́ àwọn àfikún ohun èlò wà fún àwọn ẹgbẹ́ kan pàtó, bí àwọn òwò?**
CDC ń pèsè ìwífún lọ́wọ́lọ́wọ́ nípa COVID-19 ní cdc.gov.

**Àwọn Òwò**
https://www.cdc.gov/coronavirus/2019-ncov/specific-groups/guidance-business-response.html

**Àwọn Obìnrin Olóyún, àwọn tó ń fún ọmọ lọ́yàn, àti àwọn ọmọdé**
https://www.cdc.gov/coronavirus/2019-ncov/specific-groups/pregnant-women.html

**Àwọn Ilé Ìwé**
https://www.cdc.gov/coronavirus/2019-ncov/community/schools-childcare/guidance-for-schools.html

**Àwọn Arìǹrìnàjò**
https://www.cdc.gov/coronavirus/2019-ncov/travelers/faqs.html

**Àwọn Àfikún Ọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀**
Láti gba ímeèlì ọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀ nípa COVID-19, ṣàtẹ̀wọlé àdíréẹ̀sì ímeèlì rẹ kí o sì tẹ "COVID-19" sínú àpótí àwári ní URL yí:
https://tools.cdc.gov/campaignproxyservice/subscriptions.aspx?topic_id=USCDC_2067